
**Láti Ọwọ́ Ààrẹ Dieter F. Uchtdorf**
Olùdámọ̀ràn Kejì nínú Àjọ Ààrẹ Ìkínní



# Gbogbo Rẹ̀ Dára

Bí mo ṣe ńronú nípa ogún àwọn olùlànà wa, ìkan lára àwọn ohun tí ó ńrìn jù tí ó wá símí lọ́kàn ní orin "Wá, Wá, Ẹ̀yin Ènìyàn Mímọ́" (*Àwọn Orin,* no. 30). Àwọn tí wọ́n rin ìrìnàjò gígùn náà lọ sí Àfonífojì Salt Lake máa ńkọrin yí nígbàkugbà tí wọ́n bá ńrìn.

Mo mọ̀ dáadáa pé gbogbo rẹ̀ kò dára pẹ̀lú àwọn Ènìyàn Mímọ́ wọ̀nyí. Wọ́n ní ìyọnu nípa àìsàn, ooru, rírẹ̀, òtútù, ẹ̀rù, ebi, ìrora, iyèméjì, ati pàápàá ìkú.

Ṣùgbọ́n bí ó tilẹ̀ jẹ́pé wọ́n ní gbogbo èrèdí láti kígbe, "Gbogbo rẹ̀ kò dára," wọ́n mú ìwà kan gbèrú tí a kò lè ṣaláì fẹ́ràn lóní. Wọ́n ńwòye kọja àwọn ìdàmú wọn sí àwọn ìbìkún ayérayé. Wọn fi ìmoore hàn nínú àwọn ipò wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́pé ó hàn gbangba sí ìdàkejì, wọ́n kọrin pẹ̀lú gbogbo ìgbàgbọ́ ọkàn wọn, "Gbogbo rẹ̀ dára!"

Ìyìn wa fún àwọn olùlànà jẹ́ kòròfo tí kò bá fi ìronú hàn ní iha tiwa. Mo dárúkọ díẹ̀ lára àwọn ìwà wọn tí ó fún mi ní ìmísí bí mo ṣe ńgbìrò ìrúbọ wọn àti ìfọnkànsìn.

**Àánú**

Àwọn olùlànà tọ́jú ara wọn láìka ti ìbákẹ́gbẹ́, ètò ọrọ ajé, tàbí ìrírí òṣèlú sí. Pàápàá nígbàtí ó nfa ìgbéga wọn sẹ́hìn, fa àìrọrun, tàbí túmọ̀ sí ìrúbọ ara ẹni àti làálàá, wọ́n ran ara wọn lọ́wọ́.

Nínú ayé tí ìfojúsí ńdarí àti ayé ojúṣãjú wa, ìgbìrò ẹnìkọ̀ọ̀kan tàbí ti ẹgbẹ́ le mú ipò ìṣaájú lórí ìtọ́jú àwọn ẹlòmíràn tàbí fífún ìjọba Ọlọ́run lókun. Ní àyíka ti òde òní, dídé awọn àyè ìfojúsí ọgbọ́n-orí kan pàtó le dàbíi òṣùwọ̀n bí a ṣe yẹ tó.

Gbígbékalẹ̀ àti ṣíṣe àṣeyege ìfojúsí lè jẹ́ ohun ìyanu. Ṣùgbọ́n nígbàtí àṣeyege ní dídé ibi ìfojúsí bá ńwá ní nípa àìkàsí, ìpatì, tàbí dídá àwọn ẹlòmíràn lóró, iye àṣeyege náà lè níye lórí jù bí ó ti yẹ lọ.

Àwọn olùlànà náà tọ́jú àwọn wọnnì tí wọ́n wà nínú ẹgbẹ́ wọn, ṣùgbọ́n bákannáà wọ́n gbèrò àwọn wọnnì tó wá lẹ́hìn wọn, wọ́n gbin àwọn ohun ọ̀gbìn fún àwọn ọkọ̀ ẹrù tí ó tẹ̀lé wọn.

Wọ́n mọ okun ẹbí àti àwọn ọ̀rẹ́. Àti pé nítorí wọ́n gbékẹ̀lé ara wọn, wọ́n di alágbára . Àwọn ọ̀rẹ́ di ẹbí

Àwọn olùlànà sìn bíi ìrántí rere ìdí tí a gbọ́dọ̀ fi já kúrò nínú àdánwò láti ya ara wa sọ́tọ̀ àti, dípò bẹ́ẹ̀, nawọ́ láti ran ara wa lọ́wọ́ àti láti ní àánú àti ìfẹ́ fún ara wa.

**Iṣẹ́**

"Wá, wá, ẹ̀yin Ènìyàn Mímọ́, máṣe bẹ̀rù làálàá tàbí iṣẹ́."

Gbólóhùn yí di orin ìyìn kan sí àwọn onírẹ̀wẹ̀sì arìnrìn àjò. Ó jẹ́ ìṣòrò láti fi ojú inú wo bí àwọn ọkàn ńlá wọ̀nyí ti ṣiṣẹ́ àṣekára sí. Rírìn jẹ́ ìkan lára àwọn ohun tí ó rọrùn tí wọ́n ṣe. Gbogbo wọn ní láti parapọ̀ láti pèsè oúnjẹ, ṣe àtúnṣe àwọn ọkọ̀ àkẹ́rù, tọ́jú àwọn ẹranko, ṣe ìtọ́jú àwọn aláìsàn àti aláìlera, wá omi rí kí wọ́n sì gbé e, àti dáàbò bo ara wọn lọ́wọ́ àwọn ewu ìpìlẹ̀ àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ewu inú aginjù.

Wọ́n á jí dìde láràárọ̀ pẹ̀lú àwọn èrò tí ó ní ìtumọ̀ tí ó dájú àti awọn ìfojúsí tí ó yé gbogbo ènìyàn: láti sin Ọlọ́run àti ọmọnìkejì wọn àti láti dé inú Àfonífojì Salt Lake. Ní ojoojúmọ́ àwọn èrò wọnnì àti ìfojúsí dájú sí wọn; wọ́n mọ ohun tí wọ́n nílò láti ṣe àti pé ìtẹ̀síwájú ọjọ́ kọ̀ọ̀kan ṣe pàtàkì.

Ní ìgbà tiwa—nígbàtí ọ̀pọ̀ nkan tí a fẹ́ wà ní àrọ́wọ́tó wa nírọ̀rùn —ó máa njẹ́ àdánwò láti yí sí ẹ̀gbẹ́ tàbí ṣe àròpin nígbàkugbà tí ó bá dàábí pé ọ̀nà wọ́ díẹ̀ tàbí tí

gẹ̀rẹ́gẹ̀rẹ́ ókè ńyọ̀ níwájú wa. Ní àwọn àsìkò wọnnì, ó lè mísí wa láti ronú jinlẹ̀ lórí àwọn wọnnì ọkùnrin, obìnrin ati awọn ọmọdé tí kò gba àìsàn, làálàá, ìrora, àti ikú pàápàá láyè láti dá wọn dúró ní ipá ọ̀nà tí wọ́n yàn.

Àwọn Olùlànà kọ́ ẹ̀kọ́ pé ṣíṣe àwọn ohun líle ńmú ìdàgbàsókè ati okun fún ara, inú, àti ẹ̀mí; gbé níní òye ti ìwà ọ̀run wọn ga; àti mímú àànú wọn fún àwọn ẹlòmíràn gùn síi. Ìwà bánbákú yí mú ọkàn wọn dúró ó sì di ìbùkún fún wọn ní ìgbà pípẹ́ lẹ́hìn tí rírìn wọn sọdá pẹ̀tẹ́lẹ̀ àti àwọn òkè ti parí.

#### Níní Ìrètí

Nígbàtí àwọn olùlànà náà ńkọrin, wọ́n fọhùn ẹ̀kọ́ kẹ́ta: "Ṣùgbọ́n pẹ̀lú ayọ̀ tẹ̀síwájú ní ọ̀nà rẹ."

Ó jẹ́ ìkan lára àwọn àpárá ńlá ti ọjọ́ wa pé a jẹ́ alábùkún pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àti pé síbẹ̀síbẹ̀ a lè banújẹ́ gan an. Ìyanu ti ṣíṣe rere àti ohun ìgbàlódé tó bò wá mọ́lẹ̀ àti rọ̀jọ̀ lé wa pẹ̀lú ààbò, ìdánilárayá, ìgbádùn ojúkannáà, àti ìrọ̀rùn. Àti pé síbẹ̀síbẹ̀ káàkiri àyika wa gbogbo ní a ti rí ìbànújẹ́ tí ó pọ̀ gidi.

Àwọn olùlànà náà, awọn ẹnití wọ́n ṣe ìrúbọ lọ́pọ̀lọpọ̀, lọ láìní ebi sì pa wọ́n àní fún awọn ohun tí ó jẹ́ kòṣeémání jùlọ láti yè. Wọ́n ní òye pé ìdùnún kìí wá gẹ́gẹ́bí àbájáde oríre tàbí ìjàmbá. Ó dájú gan an pé kìí wá nípa mímú gbogbo èrò wa wá símúṣẹ. Ìdúnnú kìí wá nípa àwọn ipò ní òde. Ó ńwá láti inú —láìka nkan tí ó ńṣẹlẹ̀ nítòsí wa sí.

Àwọn olùlànà mọ̀ èyinì, àti pẹ̀lú ẹ̀mí náà, wọ́n rí ìdùnnú nínú gbogbo ipò àti nínú gbogbo ìdánwò —àní nínú àwọn ìdánwò wọnnì tí ó dé ilẹ̀ tí ó sì dàmú awọn omi jíjìn ti ọkàn wọn gan an.

#### Àwọn Ìdánwò

A máa ńfi ìgbà míràn wo ẹ̀hìn lórí nkan tí àwọn olùlànà fi ara dà àti pẹ̀lú ìtura sọ pé, "Mo dúpẹ́ inúrere pé èmi kò gbé ní ìgbà náà." Ṣùgbọ́n ó yàmílẹ́nu tí àwọn onígboyà olùlànà wọnnì, kání wọ́n lè rí wa lóní, lè má fọ irú ohùn àníyàn kannáà.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìgbà àti ipò ti yípadà, àwọn ẹ̀kọ́ ìpìlẹ̀ fún dídojúkọ àwọn ìdánwò àti fífi yíyege gbé papọ̀ bíi olùtọ́jú àti olùṣe déédé agbègbè lábẹ́ Ọlọ́run kò yípadà.

Láti ọ̀dọ̀ àwọn olùlànà a lè kọ́ láti ní ìgbàgbọ́ àti ìgbẹ́kẹ̀lé nínú Ọlọ́run. A lè kọ́ láti ní àànú fún àwọn ẹlòmíràn. A lè kọ́ pé iṣẹ́ àti ìṣòwò ńbùkún wa kìí ṣe ní ti ara nìkàn ṣùgbọ́n níti ẹ̀mí. A lè kọ́ pé ìdùnnú wà fún wa bí ó ti wù kí àwọn ipò wa rí.

Ọ̀nà tí ó dára jùlọ tí a fi lè bu ọlá kí a sì fi ìmoore hàn sí àwọn olùlànà ni láti fi sínú ayé tiwa náà ìṣòótọ́ sí àwọn òfin Ọlọ́run, àànú àti ìfẹ́ fún ọmọnìkejì wa, àti ìṣòwò, ìṣe déédé, àti ayọ̀ tí àwọn olùlànà fi hàn dáadáa gan an nínú ayé ti ara wọn.

Bí a ṣe ńṣe bẹ́ẹ̀, a lè la àwọn ọdún mẹ́wá ti ìgbà sọdá, mú ọwọ́ àwọn akọni olùlànà wọnnì nínú tiwa, kí a sì fi àwọn ohùn tiwa kún tiwọn bí a ṣe ńkọrin pẹ̀lú wọn: "Gbogbo Rẹ̀ Dára! Gbogbo rẹ̀ dára!"

---

#### Ẹ̀KỌ́ LÁTI INÚ Ọ̀RỌ̀ YÍ

Ó lè fẹ́ láti bẹ̀rẹ̀ nípa kíkọ "Wá, Wá, Ẹ̀yin Ènìyàn Mímọ́" (*Àwọn Orin,* no. 30) pẹ̀lú àwọn wọnnì tí o ńbẹ̀wò. Ó lè ṣe àbápín ìrírí kan nígbàtí ìwọ tàbí ẹnìkan tí o mọ̀ ti mú àwọn ìpìlẹ̀ ẹ̀kọ́ wọ̀nyí lò ti àànú, iṣẹ́, tàbí ìṣe déédé. Tí ó bá gba ìṣílétí, ó lè jẹ́rí ti àwọn ìbùkún tí ó ńwá láti inú gbígbé àwọn ẹ̀kọ́ ìpìlẹ̀ wọ̀nyí kí o sì ṣe ìlérí fún àwọn wọnnì tí ẹ̀ ńbẹ̀wò pé wọ́n lè gba irú àwọn ìbùkún bákannáà.

## ỌDỌ́

### Pípa Àkọsílẹ̀ Mọ́

Àarẹ Uchtdorf ṣe àfiwé ọjọ́ wa sí ìgbà ti àwọn olùlànà. Nígbàtí o lè má níláti sọdá ní pẹ̀tẹ́lẹ̀, o dàbí àwọn olùlànà ju bí ó ṣe rò lọ! Bákannáà o lè fi àànú, iṣẹ́ takuntakun, àti ìṣe déédé hàn. Àti pé gẹ́gẹ́bí a ti mọ̀ pé àwọn olùlànà ṣe àpèjúwe àwọn ìwà wọ̀nyí nítorí ti àwọn àkọsílẹ̀ tí wọ́n ti pámọ́, àwọn àtẹ̀lé rẹ lè mọ̀ ọ́ nípa ìwé ìròhìn tìrẹ náà.

Mú ìṣẹ́jú díẹ̀ láti kọ àkọsílẹ̀ kékeré nípa ara rẹ nínú ìwé ìròhìn rẹ. O lè kọ nípa àwọn ohun ti ẹ̀mí, gẹ́gẹ́ bí o ṣe jèrè ẹ̀rí rẹ tàbí borí àwọn ìpèníjà pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Bàbá Ọ̀run. Bákannáà o lè ran àwọn ọmọ ọmọ ọmọ rẹ lọ́wọ́ (àwọn ẹnití ó lè ka ìwé ìròhìn rẹ lọ́jọ́ kan!) Láti mọ bí ìgbé ayé rẹ ojojúmọ́ ṣe rí. Àwọn iṣẹ́ wo ní ò ńṣe ní ilé ìwé? Báwo ni wíwò yàrá rẹ ṣe rí? Kíni ìrántí tí ẹbí rẹ tí o gbádùn jùlọ?

Gẹ́gẹ́bí ó ṣe bẹ̀rẹ̀ kíkọ díẹ̀ díẹ̀ lójojúmọ́, ìwọ kì yíò lè ríi kedere síi bí Bàbá Ọ̀run ṣe ńràn ọ́ lọ́wọ́ nípa ìgbé ayé ojojúmọ́ nìkàn, gẹ́gẹ́bí Ó ṣe darí àwọn olùlànà, ṣùgbọ́n ìwọ yíò fi ogún kan sílẹ̀ bákannáà fún àwọn àtẹ̀lé ti ara rẹ tí ó ńbọ̀ ní ọjọ́ iwájú.

## ÀWỌN ỌMỌDÉ

# Títẹ̀lé Àpẹrẹ Àwọn Olùlànà

Àrẹ Uchtdorf ṣe àbápín àwọn ọ̀nà díẹ̀ tí àwọn olùlànà fi ìfẹ́ hàn fún Bàbá Ọ̀run. O lè tẹ̀lé àpẹrẹ wọn Níbí ni àwọn ìrò díẹ̀ láti mú u yín bẹ̀rẹ̀:

**ÀÁNÚ**

☐ Kọ ìwé àànú kan tàbí tọ́jú ohun kan fún ẹnìkan tí ó ńbanújẹ́.

☐ Ṣe ìrànlọ́wọ́ fún akẹ́kọ̀ọ́ yàrá ìkàwé rẹ kan ọkùnrin tàbí obìnrin láti ṣe iṣẹ́ àmúrelé rẹ̀.

**IṢẸ́**

☐ Gbé ìfojúsí kan kalẹ̀ Ṣe ohun kan lójoojúmọ́ ní oṣù yí láti ran ọ́ lọ́wọ́ láti dé ìfojúsí rẹ.

☐ Ran àwọn òbí rẹ lọ́wọ́ láti ṣe oúnjẹ alẹ́.

**NÍNÍ ÌRÈTÍ**

☐ Ṣe ìtò lẹ́sẹ̃sẹ àwọn ohun amúnúdùn mẹ́wá nínú ayé rẹ.

☐ Rẹ́rín sí gbogbo ènìyàn tí o rí.

© Ọdún 2015 Látọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀é ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/15. Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/15. Ìyírọ̀padà ti *First Presidency Message, July 2015*. Yoruba. 12587 779

# Àwọn ìwà Ọ̀run ti Jésù Krístì: Dídáríjì àti Ìyọ́nú

*Fi tàdúrà-tàdúrà ṣe àṣàrò ohun èlò yí kí o sì mọ ohun tí o ó wákiri láti ṣe àbápín. Báwo ní níní òye ìgbé ayé àti ojúṣe ti Olùgbàlà yíò ṣe mú ìgbàgbọ́ rẹ nínú rẹ̀ pọ̀si àti bùkún àwọn wọnnì tí ò ńṣe ìṣọ́ lé lórí nípa ìbẹ̀niwò kíkọ́ni? Fún ìwífúnni sĩ, lọ sí* ***reliefsociety.lds.org****.*

**Ìgbàgbọ́, Ẹbí, Ìrànlọ́wọ́**

*Èyí ni apákan ti onírurú àwọn Ọ̀rọ̀ Ìbẹniwò Kíkọ́ni tó ńfi àwọn ìwà ọ̀run ti Olùgbàlà hàn.*

Níní òye pé Jésù Krístì ti ní ìdáríjì àti ìyọ́nú sí wa le rànwá lọ́wọ́ láti dáríjì àti láti nawọ́ ìyọ́nú sí àwọn ẹlòmíràn. "Jésù Krístì ni Alápẹrẹ wa," ni Ààrẹ Thomas S. Monson sọ. "Ìgbé ayé Rẹ̀ jẹ́ ogún ti ìfẹ́. Aláìsàn ni Ó wòsàn; àwọn tí a tẹ̀mọ́lẹ̀ ni Ó gbé sókè; ẹlẹ́ṣẹ̀ ni Ó gba là. Ní ìparí àwọn olùbínú ènìyàn-kénìyàn gba ẹ̀mí Rẹ̀. Síbẹ̀síbẹ̀ àwọn ọ̀rọ̀ ńdún láti òkè Gọ́lgọ́tà: 'Bàbá, dáríjì wọ́n; nítorí wọn kò mo ohun tí wọ́n ńṣe' —ìrí ìdádé kan ní ayé ikú nípa àánú àti ìfẹ́."[1]

Tí a bá dárí ẹ̀ṣẹ̀ ji àwọn ẹlòmíràn, Bàbá wa Ọ̀run bákannáà yíò dáríjì wá. Jésù sọ fún wá kí a "ní àánú, gẹ́gẹ́bí Bàbá yín ti ní àánú bakannáà" (Luke 6:36). "Ìdáríjì fún *àwọn ẹ̀ṣẹ̀* wa ńwá pẹ̀lú àwọn ipò," ni Ààrẹ Dieter F. Uchtdorf, Olùdámọ̀ràn Kejì nínú Àjọ Ààrẹ Ìkínní sọ. " A gbọ́dọ̀ ronúpìwàdà. . . .Njẹ́ gbogbo wa kò fi, ìgbà kan tàbí òmíràn, ti fi ìrẹ̀lẹ̀ dé ìtẹ́ àánú tí a sì bẹ̀bẹ̀ fún oore ọ̀fẹ́ bí? Njẹ́ a kò ti nífẹ́ pẹ̀lú gbogbo agbára ọkàn wa fún ìyọ́nú—láti gba ìdáríjì fún àwọn àṣìṣe tí a ti ṣe àti àwọn ẹ̀ṣẹ̀ tí a ti ṣẹ̀ bí? . . .Fi àyè gba Ètùtù Krístì láti yí ọkàn rẹ padà kí ó sì wò ọ́ sàn. Ẹ fẹ́ràn ara yín Ẹ dáríji ara yín."[2]

## Àfikún àwọn Ìwé Mímọ́

Máttéù 6:14–15; Lúkù 6:36–37; Álmà 34:14–16

## Láti inú àwọn Ìwé Mímọ́

"A níláti dáríjì àní bí a ṣe ńgba ìdáríjì," ni Alàgbà Jeffrey R. Holland ti Iyeju àwọn Àpóstélì Méjìlá sọ.[3] Ìtàn ti ọmọ onínákúná fi ẹ̀gbẹ́ méjèèjì ti ìdáríjì hàn wá: wọ́n dáríjì ọmọ kan ọmọ míràn sì ńtiraka láti dáríjì.

Èyí àbúrò gba ohun ìní rẹ̀, ó náa kíákíá, nígbatí ìyàn dé, ó ṣiṣẹ́ ó ńbọ́ àwọn ẹlẹ́dẹ̀. Àwọn ìwé mímọ́ sọ pé "nígbàtí orí rẹ wálẹ̀," ó padà sílé ó sì sọ fún bàbá rẹ̀ pé òun kò yẹ ní ẹni tí a bá máa pè ní ọmọ rẹ̀ mọ́. Ṣùgbọ́n bàbá rẹ̀ dáríjìí ó sì pa ẹgbọrọ màlúù àbọ́pa fún àríyá. Ọmọ rẹ̀ ẹ̀gbọ́n padà láti ibi iṣẹ́ nínú pápá ó sì bínú. Ó rán bàbá rẹ̀ létí pé òun ti sìn ín fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ 'láì rú àwọn ófin, síbẹ̀síbẹ̀ "ìwọ kò sì tĩ fi ọmọ ewúrẹ́ kan fún mi, láti fi ṣe àríyá" Bàbá náà fèsì, "Ọmọ nígbà gbogbo ni ìwọ ńbẹ lọ́dọ̀ mi, ohun gbogbo tí mo sì ní, tìrẹ ni. O yẹ kí a ṣe àríyá, kí a sì yọ̀: nítorí àbúrò rẹ yí ti kú, ó sì tún yè, ó ti nù, a sì rí i" (see Luke 15:11–32).

**ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Thomas S. Monson, "Ìfẹ́ ni àkójá Ìhìnrere," *Atọ́nà,* Oṣù Kárún Ọdún 2014, 91.
2. Dieter F. Uchtdorf, "Oníyọ́nú Ńgba Ìyọ́nú," *Atọ́nà,* Oṣù Kárún Ọdún 2012, 70, 75, 77; àtẹnumọ́ nínú àtẹ̀tèkọ́ṣe.
3. Jeffrey R. Holland, "The Peaceable Things of the Kingdom," *Ọ̀págun,* Oṣù Kọkànlá Ọdún 1996, 83.

### Gbèrò Èyí

Báwo ni ìdáríjì ṣe lè fún ẹni tí ó ńdáríjì ní èrè?

© Ọdún 2015 Látọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved Tí a tẹ̀ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/15 Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/15. Ìyírọ̀padà ti *Visiting Teaching Message, July 2015.* Yoruba. 12587 779